# ELETI OFE

'A-NJU-WON KO ṢE WI LEJỌ'

VOL. XIV NO 950 LAGOS SATURDAY DECEMBER 5 — DECEMBER 11 1964 KOBỌ MEJI (2D)

## Ibosi Ole!!!

# Gbomo - Gbomo Wo Ilu Eko

IBADAN — Ogaulọgọ enia ni awọn sa are lọ si ibudo ọkọ ojurin ni ilu Ibadan ni ọjọ alamisi ti se ọjọ kẹta oṣu yi lati lọ wo bi ọmọ awọn ti o sọnu le wa larin awọn ọmọ yi.

Ọkunrin Ibo kan ti oruko rẹ jẹ Arisa Aku ti o nti iha Oke Oya rekọja lọ si ilu Eko pẹlu awọn ọmọ wẹrẹ mẹrindinlogun ti ọjọ o i awọn ko ju ọmọ ọdun mẹsan si mẹdogun lọ.

Awọn ọlọpa da ọkunrin ni duro si Ibadan nwọn si gba gbogbo awọn ọmọ nwọnyi kuro ni ọwọ rẹ fun itọju.

Awọn ọlọpa ti da ọkunrin Ibo na duro si ọdọ ni Ibadan fun iwadi, Ọlọpa ni awọn ti nwọn ri ni ọdọ ẹ jẹ ọmọ Hausa ati Ibo.

## NNA Yio Da Awolowo Sile Bi ?

ONDO — Okan ninu awọn aṣiwaju ẹgbẹ NNA, Oloye R.A. Fani-Kayọde sọ ninu ipolowo ibo rẹ ni ilu Ondo larin ogunlọgọ enia pe, Egbẹ asepọ NNA yio da Oloye Awolọwọ silẹ kuro ninu ẹwọn ti ẹ ba dibo fun ẹgbẹ na lati gba ijọba apapọ.

Oloye Fani-Kayọde sọ wipe "A o ju Oloye Awolọwọ silẹ kuro ni ile ẹwọn nitoripe o si ni ọpọlọpọ rerelati ṣe fun wa." Igbakeji Olotu iwọ Orun ni dajudaju Oloye Awolọwọ wa ninu ẹniti yio mu idagba soke ilẹ wa lọ si iwaju ti o ba wa ni arin wa.

Oloye Fani-Kayọde ni oti iṣelu ki ṣe iba ara ẹni ja ni ẹmi iwọ, bi ko ṣe wipe ija ni imoran ati eto Iṣẹ ilu. O ni on ko ri idi rẹ bi a tiṣe le sọ ọtẹ oṣelu di olori di ori re mu, ti yio si da nkan ti ko le tan silẹ,

O ni ẹgbẹ NNDP wa lati ra iyi ọla ati ogo Yoruba ti o ti sọnu pada.

## Awon Ore Meta Ti Nwon Ko Le Yara Won

A dupẹ pupọ fun ẹyin ti nka iwe wa ni Ọse Ọse, dajudaju itan ti a so koja jẹ ar kọgbọn fun enikẹni ninu wa. Bo ilẹ jẹ pe Orọ Ọlọmọ ko ṣe gbọ ṣe ọmọ ni a pe oruko tan na, gbogbo wa ri wipe a tun kọ ọgbọn meji miran ninu rẹ. (1) Obinrin ko ṣe fi inu han, (2) Orun san iku.

Yio dun mọ ni bi iwọ ti ka ba le fi ṣe ọgbọn pe bi o ti wu ki o fẹran iyawo rẹ to o ko gbọdọ fi aṣiri rẹ han.

Itan ti abẹrẹ ni ọsẹ yi jẹ itan kan pataki ti o mu ẹkọ gidi wa, yio dara ti o ba ka iru awọn itan ba yi ni arin awọn ọmọ, Aya ati ẹbi rẹ.

Ọkunrin kan wa oruko rẹ n ma jẹ Eyi Owu Awi ti Ọlọrun ni asẹ. Lati kekere rẹ ni o ti gbe oruko na e ori gbogbo ti si mọ ti ile ti oko ọkunrin na ni iyawo kan ti o

( Wo yoku loju ewe kefa )

## Oba Oni Yo Ara Re Kuro Loro Awolowo

IBADAN – ONI ti ilu Ifẹ ọlọla Adesoji Aderẹm sọ fun awọn oni iwe iroh ni ilu Ibadan ngbati awọn bere lọwọ rẹ nipa eto ipari ija ti o wa larin oloye Awolọwọ ati oloye Akintọla.

( Wo yoku loju ewe kẹfa)

# ELETI – OFE

(A NJU WỌN KO ṢE WI LEJO)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME

28, Kosoko Street; Lagos, "ELETI-OFE" Lagos

P. O. Box 467, Phone 23370

VOL. XIV NO 950 SATURDAY Dec. 5 - Dec. 11 1964.


# Ibukun Ni Fun Awon Olopa

A dupe pupọ fun awọn ọlọpa wa fun idagba soke iwadi awọn olosha ilẹ wa ti o ṣe wipe osan gangan ni nwọn tun ṣe iṣẹ ọlọsha wọn pẹlu ibọn, ed ati awọn ikan ọsẹ ti o ran.

O da wa nị oju p ọna tị awọn ọlọpa wa g b a lati wadị owo ti awọn ọlọsha jigbe ni Ikeja ni lọlọ yi je ọna pataki tị a fi nwa ịdi nkan.

Iru Ogun tị awọn ọlọsha yi gbe si a w ọ n ọlọpa nịgbati nwọn lọ lati fi iwe aṣẹ w a ile ati o h u n ịni nwọn je iyalẹnu fun awọn ọlọpa papa lati ri w i p e bi awọ ko ba mura dada awọn ọlọsha fẹ gbe ogun tị awọn na.

Ni ẹhin ti Ikẹja ni nwọn tun lọ dana f u n ọ g a awọn oṣiṣẹ kan ni iha Benin, tị nwọn si ja ẹgbẹrun pọun ọ na mejị gba nị ọwọ rẹ

Nitori eyi a tun bẹ ẹyịn ọlọpa wa kị e ma se ṣe are tịtị oluwa yịo fi fun yin ni iṣẹgun l'ori awọn majekarin iọsan majekasun ni oru nwọnyị.

Mo bẹ ẹyịn ara ịlu papa lati fun awọn ọlọpa w a ni ịranlọwọ gbigbọ, mimu ati ifurasi nigba y o wn ti ikan ninu mẹta yi ba bọ si ọdọ yin

# Balewa Si Ona Oju Irin Bornu

BORNU — Olotu ijọba Apapọ ti ilẹ wa nị o sị ọna ọkọ oju irin ti a fi owo ịyebiye ṣe lọ si ilẹ Bornu ni ọjọ Monde ọgbọn ọjọ oṣu ti o koja.

Ninu ọrọ rẹ, o fi han awọn enia pataki ti nwọn wa ibi eye na pe oju ọna ọkọ oju irin titun yi je iyanran kan pe asiko ijọba on ni a se on ti o dara yi.

( Wo yoku lo'ju ewe karun )

# Awon Eni Ifura Yin Ibọn Si Awon Olopa

EKO — Awọn ọlọpa fi ye wa pe awọn lọ si adugbo kan ti a npe ni Ikate ni ilu Eko pẹlu iwe iwadi ti ijọba. Nwọn ṣe eyi lati fi wa Idi bawo ni owo ti awọn ọlọsha gbe ni Ikẹja ni ọsẹ ti o kọja.

A gbọ wipe nigbati awọn ọlọpa ọtẹlemuyẹ de inu ile ti nwọn fẹ ṣe abẹwo rẹ yi, Nwọn ko gba awọn ọlọpa ni aye lati wọ ile, Nṣe ni nwọn ti ilẹkun mọ ara nwọn.

Nigbati o ṣe awọn enia ti o wa ninu ile na ṣi ilẹkun ni ojiji wọn si bẹrẹ si yin ibọn si awọn ọlọpa awọn ọlọpa papa bẹrẹ si yịn ịbọn ti nwọn awọn enịa nwọnyi bẹrẹ si fi ẹhin rin lati sa lọ.

A gbọ wipe nigbati awọn ọlọpa wọ ile awọn enia meji ninu wọn fi ara pa nwọn si wa ni ịle iwosan nị Eko fun itọju.

Lẹhin eyi awọn ọlọpa bẹrẹ si wa ile na wọ, nwọn ri ogalogọ owo ko ninu re ; Awọn ọlọpa fi ye oniwe irohin pe awọn ro wịpe owo na jẹ apakan nịnu owo ti nwọn ji gbe ni Ikẹja ni ịLiṣẹ awọn ọkọ ofurufu.

Nwọn tun ri awọn ibọn pupupu meji ( Revolvers) nịnu ịle na, a nị ero wipe awọn ịbọn nwọnyị jẹ ara eyi ti nwọn lo nị Ikẹja.

Awọn ọlọpa fi ye wa pe ọkan nịnu awọn ti nwọn ri mu tị ṣe iṣẹ ọlọpa ri.

## Oba Awujale Bebe Fun Ifi Owo So Owo

IJẸBU - O D E — Alhaji Ọba Olukayọde Adetona ti nṣe ọba Awujalẹ ti ịlu Ijẹbu-Ode, ṣe ikilọ f u n

(Wo yoku loju ewe karun)

# E Se Ri Awon Omo Kekeke Kuro Ninu Ote

EKO – Awọn ọlọpa tun fi ikilọ si ode ni ori awọn ọmọ wa kekeke ti nwọn fẹ ri owo ati ẹsẹ wọn sinu o ṣ e l u. nwọn ni awọn k e si ẹyin obi tabi alagbatọ lati ṣẹri awọn ọmọ yin kekeke kuro nịbi iwa tẹmbẹlẹkun ni arin ilu tabị n ị adugbo.

Ọga awọn ọlọpa ni eniti ndari eto ẹkọ ti ị j ọ b a apapọ sọ wịpe on ti fara sị ịwa ti awọn ọmọ ile iwe nbu nipa ọṣelu to sị jẹ nkan ti o ni ewu nịnu ni fun nwọn

Awọn ọlọpa ni awọn ọmọ kekeke nị awọn ilu nla nla, papa ni ilu Eko, nwọn a ma gbe egungun, agẹmọ, agere tabi Abe, nwọn sị gbe aṣịya dani pẹlu ami

( Wo oju ewe karun )

# Omo Adorin Odun Lo Se Ewon

AKURE — Ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Company Ọmọṣọ ẹniti nṣe ọmọ adọrin ọduu ni awọn ọlọpa mu wa si iwaju Onidajọ awọn ọlọpa pẹlu ẹnikan ọmọ ọduu mej dinlọgbọn ti a npe oruko rẹ ni Fransis Chukuma fun ẹsun pe, awọn ọkunr n mejeji yi da oko si ileto kan ti a npe ni Kajọla ni iha Ikọle-E·iti nwọn gbin ewe ti a npe ni igbo, nwọn si ko ewe na jọ bi o ni ẹgbẹrun pọnọ ọgọrun pọun.

Adajọ ni nwọn jẹbi ẹsun na, ki Company Ọmọṣọ lọ ṣe ẹwọn ọdun mẹta pẹlu iṣẹ aṣekara. Bakanna onidajọ ni ki Fransis Chukuma lọ ṣe ẹwọn ọdun meji alaṣekara.

# Oga Ilewe Wa Ninu Danadana

BENNIN—Oludari eto ilewe ti o si jẹ pe on na ni Olukọ agba ni St. Marlins Grammer School, Ogowashi-Uku Ọgbẹni Martin Biose, pẹlu awọn mẹfa kan ni a mu wa si iwaju onidajọ ni kotu ọlọpa ti ilu Be·in fuu ẹsun mẹfa. Ikan ninu ẹsun na ni pe nwọn da ọna, larin Benin si ilu Asaba ni dede agogo mẹrin oru ni ọjọ kọkanlelogun oṣu ti o kọja,

Ẹsun pe a ri ibọn ṣakabula meji gba ni ọwọ nwọn Irin ti a fi nfọ ile tabi ṣọbu ti a rọ ni ilẹ wa, Irin nla ti a fi nyọ iṣo nla tabi ti a fi wọn apoti nla tabi ilẹkun, olu irin kan ada kan ati fitila ina oni mamamana ti a ma ntan da ni meji.

Ikan ninu awọn ọdaran yi ni a tun fun ni ẹsun pe. a ba awọn aṣọ ọlọpa ni ara rẹ, pẹlu ami ijẹri ọlọpa, Iwe akọlẹ ti awọn ọlọpa, ponpo ọlọpa, fila ojo ati ami igbaya ọlọpa. Nwọn ni awọn ko jgbi.

Agbẹjọro Ọgbẹni F.H. Eduvie ti nṣe ẹhin de agbẹjọro nwọn Ọgbẹni Chukura ni ki a gba idur› fun Martin Biose ẹn·t· nṣe ọga ile ẹkọ lati ·ọ tọju awọn ọmọ ile ẹkọ rẹ fun idanwo.

Adajọ ngb· kọ iduro fun gbogbo nwọn, O ni ki nwọn wa ni itimọle labẹ awọn ọlọpa.

# Nwon Lu Atuko Mato Kan Pa

OGIDI - Irohin kan wa lati ilu Onitsha pe ọ·unrin kan ti a npe ni Alexander Anielo ti o si jẹ a tu ọkọ mato fi Onitsha silẹ lọ si Nka·agu ni ọjọ Satide. Nigbati o de ilu kan ti a npe ni Ogodi, o da mato rẹ duro. o wa si eba ọna.

Ni ibiti o ti nsinmi ni awọn ọmọ janduku ti awọn oṣelu wa ba a, nwọn ni o gbe mato rẹ di ọna fun awọn ṣugbọ·ı ki ọkunrin na to fun nwọn ni esi nwọn ti bẹrẹ si lu kikan kikan ti o si fi da ku.

Nwọn gbe ọkunrin na si inu mato nwọn wa lọ si ile iṣegun nla ti ilu Onitsha, o si ku lẹhin wakati diẹ ti a gba si ibẹ.

# Oko Ojurin Pa Obinrin Kan

KADUNA —Ọmọ obinrin kan ti nṣe ọmọ ọdu· mẹrundinlogoji ti orako rẹ njẹ Kutuk Kwazı, o jẹ iran kaje ni ilẹ Kafanchan, ·ı ẹba Kaduna.

Obinrin yi gbe ẹru kan ·ı owuwo le ori rẹ o si nrin ni eti oju irin ti nṣe ọkọ n· i·ọn agogo meji ọganjọ oru, nigbati ·ṣẹlẹ yi de wa ba a.

# Wo·ı Sa Iya Ati Omo Re Pa

IJARE — Ni Abule kan ti a npe ni Ijare nı agbegbe A·urẹ ni a gbọ wipe ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Akanbi ṣ obinrin kan ti oruko rẹ njẹ Aiyeola Adedun pẹlu awọn ọmọ rẹ meji pa ni dede agogo mẹwa orọ ọjọ Sunde i ṣe ọjọ kọkọnd··l··ıbọn oṣu y·

Awọn Ọlọpa koi ti fi han wa ikan ti o ṣe t ọkunrin na na fi pa obinrin yi ati awọn ọmọ rẹ. Ọmọbinrin kan ti a npe ni Olomi Ojo ti o gbe ilẹ kanna pẹlu Aiyeola fi ara gba ninu ọgbẹ n·a. O wa ni ile Iwosan ni Akurẹ fud itọju.

Ọkunrin Akanbi ti a gbọ pe o ṣe ọrọ yi ti a lọ ọwọ awọn ọlọpa koi ti tẹ.

## Omo Ile Wa Meji Wo Ewon Ni Ilu Oyinbo

LONDON - Awọ· ọmọ ilẹ wa mej t · mu fun ẹsun pe nwọn ko igbo wọ ilu Oyinbo ni a da ni ẹjọ ni ilu

(Wo yoku loju ewe kẹrin)

# Atunse Larin Awolowo Ati Akintola

IBADAN – Awọn ẹgbẹ kan ni ilu Ibadan ni oruko awọn a ma jẹ Apapọ ọmọ Yoruba fun Atunse, ti Ọgbẹn Alhaji R.A Adesina da silẹ, fun a ti pari ija ti o wa ni arin Asiwaja ẹgbẹ NNDP oloye S.L Akintola a Asiwaju ẹgbẹ Action Group o l o y e Ọbafẹmi Awolọwọ.

Ọgbẹn! Alhaji Adesina ti pe ipade kan si afin Oni ni ile Ifẹ ni ọjọ alamisi ti nṣe ọjọ kẹta oṣu yi O pe gbogbo awọn ọba ilẹ Yoruba ati awọn asiwaju ẹgbẹ oṣelu pẹlu awọn enia nla ni ilu ilu.

Ninu ọrọkan ti ọgbẹni N. A. B. Kotoye ẹniti nṣe akọwe ikede f u n ẹgbẹ N NDP o ni awọn ẹgbẹ ti on ko ni imọ ko si ni ọwọ ni pa igbiyanju ti awọn ẹgbẹ Alhaji Adesina nṣe lati ṣe atunṣe ni arin oloye Awolọwọ pẹlu oloye Akintola

… ni ẹgbẹ ti Alhaji Adesina da silẹ w a lati b a nkan jẹ ni. O ni ti Alhaji Adesina ati awọn enia rẹ ba lẹ se dara-dara ati ododo pẹlu ilosiwaju ati iṣe ọkan ọmọ Yoruba, ẹ ọ … wa wọ inu ẹgbẹ NNDP lati sa a g b a r a awọn … rẹ.

Awọn ẹgbẹ ọdọ Action Group ni awọn ko fi ara mọ eto A l h a j i Adesina. Nwọn ni ẹtan ni awọn ri ruu rẹ si, lati fi da ruke ti de si lẹ larin awọn enia ti nwọn o dibo fun.

# A Ri Ibon Lowo Eni-ti Afura Si

Awọn olopa ọlẹlẹmuye ri okunrin kan mu ti nwọn fura si, nigbati nwọn ri

nwọn ba ibọn kukuru kan ni ọwọ rẹ ati ibọwọ kan. Nwọn bere ọpọlọpọ ọ r ọ ni ọwọ rẹ, lẹhin na ni nwọn mu si itimọle.

A mu ọkunrin yi nitoripe a fura si w i p e o wa ninu awọn ti awọn wa fi agbara gbe owo ni ibi iṣẹ awọn ọlọkọ ofurufu ni ọsẹ t o kọja.

Bo ya ibọn ọwọ rẹ ni a yio lati fi ko ẹrujẹjẹ b a awọn olowo yi ki wọn to le gbe owo na lọ. Bo ya ibọwọ ti … ri ni ọdọ rẹ jẹ eyi ti o lo lati fi awọn ila ọwọ rẹ pamọ ki o ma ba han ni ara ibọn.

Ọlọpa ni awọn ro wipe Okunrin ti a ri ibọn ati ibọwọ gba ni ọwọ rẹ y jẹ ikan ninu awọn alagbara mẹfa ti a w ọ n fi agbara nwọn ati ibọn gbe o w o awọn oṣiṣẹ ọkọ ofurufu.

Awọn ọlọpa inu sọ ba yi ni Ikoyi pe awọn ko yi ri awọn ẹdaran na nu ṣugbọn awọn nsa gbogbo agbara lati w a wọn ri. Awọn ọlọpa ti ṣa awọn enia kan jọ ti a si ni ki ọgbẹni Enemokwu w a yẹ awọn wo b o ya y i o ri awọn ti nwọn wa gbe owo lọwọ rẹ ninu wọn ṣugbọn a ko ti ri,

Awọn ọlọpa ni awọn … e o pe awọn olọsha … si wa ni ipamọ k a n ṣugbọn nwọn ni awọn ti a … r a si y e ran … lowo lati ri wọn.

# Olopa Ko Awon Omo Janduku

IKẸJA — Awọn ọlọpa funwa ni iro pe a w ọ n ri awọn ọmọ oni jagdijagan mẹtadinlogoji ko ni arin Ikẹja ati Mushin ni ọjọ Satide ti oṣu … ti o kọja di mejidinlọgbọn.

Awọn ọlọpa ni awọn sọ iṣẹ na ni oruko "Ko Jan duku Kuro" awọn ki yio dẹkun lati ma wa nwọn kan ki awọn si ma ko wọn kuro ni arin ilu titi ti ibo yio fi rekọja.

Ninu ile iṣẹ kan ni orere Olọrunṣogo n i i l u Mushin ni a ti ri awọn ikan ọṣẹ bi awọn ọbẹ ẹlẹnu ṣonṣo, ọbẹ, ati awọn igo ofifo, a ti k o gbogbo awọn yi lọ si ile ọlọpa.

Gbogbo awọn ti a ko ninu ile ti a ri awọn ikan ọṣẹ yi ni adaduro si ọdọ ọlọpa ni Ikẹja.

Awọn bi ogun miran ti a ri ko ini Idi Oro, ni ibudo ọkọ Bọsi, ati n i ile oti kan ni Ikẹja wa ni adaduro ni ọ d ọ ọlọpa fun iwadi.

# Mato Ja Sinu Odo

SOKOTO —. Enia mejidinlogun ni nwọn ku patapata awọn enia m e j e si fi ara pa ninu iṣẹlẹ mato kan ti nbọ lati Ṣokoto wa si ilu Ibadan.

A gbọ pe mato na fi o r i sọ afara k a n ni agbegbe ilu Gusau o si subu si inu rẹ. A w ọ n enia meje ti o fi a r a pa wa ni ile iwosan kan ni agbegbe ilu, na diẹ ninu awọn meje na si wa ninu ewu.

## A Gun Okunrin Kan Ni Obe Ni Ile Oti

ABAKALIKI — gbogbo enia ni o ti bẹrẹ si sa fun ile oti kan ni Abakaliki nigbati a gbọ wipe nibẹ ni a gbe gun ọmọkunrin kan ti o ngbadun oti pẹlu awọn ọrẹ rẹ ni ọbẹ pa. Nwọn ni Ọgbẹni Nwankwo Uda Awoke gbe ife oti rẹ si oke lati ta fere si ọna ọfun rẹ nigbati a gun ni ọbẹ ni iji.

A ri gbọ pe ariyanjiyan wa ni arin Awoke pẹlu ẹniti o gun ni ọbẹ pa lori igo oti ẹmu kan wipe Awoke ni yio san owo rẹ Awoke si ni on kọ ni yio san owo rẹ.

## Omo Ile Wa Meji Wo Ewon

(O bẹrẹ lo ju ewe kẹta)

Oyinbo ni ọjọ kini oṣu yi, Awọn ni James Ore jẹgẹdẹ ti nṣe ọmọ ọdun

(Wo oju ewe karun)

# Omo Ile Wa Meji Wo Ewon Ni Ilu Oyinbo

(O bẹrẹ loju ewe kẹ..)

logun ati Mosadi ọlanipẹkun Alli, ti nṣe ọmọ ọdun mẹrindilọgbọn. A sọ ekini kẹji nwọn si ẹwọn ọdun mẹta mẹta fun ẹsun pe a ri igbo ti o to iwọn o ni ẹgbẹgbẹrun pọnọ ... pọun ni ọwọ nwọn Adajọ ni ki a fi nwọn ranṣẹ pada si ilu nwọn.

Nwọn ifura yọ si awọn ... ile eru Customs ni ilu Oyinbo, nigbati a ri ki a san ... fun ikan ... o wa ninu ... ti ewo rẹ koju wọn ṣle dẹ lọ. Ṣugbọn nigbati a ṣi, a ri pe ewe O oro ni o wa ninu agolo na.

Awọn ọlọpa ... ti ilu Oyinbo ti han ... pe ki ko lgbo wọ ilu yi rẹ ndagba si ... ti ọdun kẹta lọ

# Oju Irin

(O bẹrẹ loju ewe keji)

Olotu ijọba Apapọ dupẹ gidigidi fun awọn enia nla nla ti a pe lati Okere ti nwọn si jẹ wa. O ni wiwa nwọn jẹ ijẹri wipe ifi ọwọ so ọwọ wa ni arin ijọba wa pẹlu awọn ilu agbegbe.

Awọn Olori ijọba ilu agbegbe nwọn yi na si ṣe Ọpẹ fun awọn ijọba wa daradara nipa ifi ọwọ so ọwọ pọ ni ilẹ awa enia alawọ dudu.

Olotu ijọba Ariwa Alhaji Ahmadu Bello ni on dupẹ pupọ fun ijọba Apapọ ti o fi ọna oju irin yi da ijọba ou ni ọla.

YOUR SPECIALIST FOR ALL
BUILDING MATERIALS
BROSSETTE
(NIGERIA) LTD.
WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA

At your service
- STOCK
- SPECIAL ORDERS
- TECHNICAL INFORMATIONS

# Bello Si Ero Omi Titun

MAIDUGURI — Ni atalata tiṣe ọjọ ki ni oṣu yi ni Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello ti ṣe Olotu ipinlẹ ariwa ṣi ile ẹrọ omi mimu titun ti a fi ọpọlọpọ owo ṣe si Bama ni iha ilu Maiduguri.

Ninu ọrọ re ọlọla Ahmadu Bello ni omi jẹ pataki ni igbesi aiye ẹda, omi na ni lati jẹ omi ti o mọ ti o dara. O ni a kole da iṣẹ silẹ ni agbegbe kan ti ko ba si omi ti a o l... ni iha ...bẹ.

Olotu na fi han awọn ara Bama pe omi titun ti aṣẹṣẹ fun yi na yio se ọpọlọpọ anfani fun ilọsiwaju ara lile ati idagba soke ilọsiwaju ilu.

Oni ẹrọ omi na yio ma fun nwọn ni galọnu omi ẹgbẹrun ọna igba ni ojojumọ, o ni ẹtọ ni pe ki nwọn sọ omi na ni lilo.

# ESERI AWON OMO 10

(O bẹrẹ loju ewe keji)

Ẹgbẹ oṣelu ni ara wọn.

Nwọn ni awọn bẹ ẹyin obi lati kilọ fun awọn ọmọ yin lati kuro ninu iwa ti ko dara yi. Awọn ọlọpa ni ti ẹ ba le mu ọmọ yin so awọn yio ba yin mu so ninu ofin akosilẹ nipa awọn ọmọde. Ofin na yio si tun kọlu ẹyin obi papa.

# Oba Awujale Bebe

(O bẹrẹ loju ewe keji)

awọn Alabojuto eto ijọba ibilẹ pe ...yio dara ti nwọn ba wa ni ifi ọwọ so ọwọ pọ pẹlu awọn obinrin ọja, o ni ki ṣe wipe awọn ti a ko kuro ... idi eto ijọba ibilẹ wọn ko ṣe ala ni gbungbungbun pẹlu awọn Obirin ọja nwọnyi, ṣugbọn ọgbọn ati eto ni nwọn fi nṣe.

Ọba Adetọna sọ eyi nigbati nwọn fi e'o awọn Olubojuto eto ijọba ibilẹ re, ti o si jẹ wipe on ni baba ẹgbẹ gbimọ na, Awujalẹ ni ki a ma ṣe ṣe ofin ti yio ko inira ati rogbodiyan wọ arin ilu, O ni on dupẹ fun alaga awọn Alabojuto yi Ọgbẹni Ọmọba Adebayọ Odubanjọ ẹniti o fi ipo nla ti o wa ni ilu Oyinbo silẹ lati wa sin ilu rẹ

Awujalẹ ni igbimọ ti on wa lati mu irọrun ilọsiwaju pẹlu ifi ọwọ so ọwọ wa si arin ilu ati agbegbe rẹ ni.

# Oba Oni Yo Ara Re Kuro Loro Awolowo

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Ọlọla Adesọji fi esi bayi "Emi ko ro wipe asiko yi nį o tọ lati sọ nkan kan nipa ọrọ Awolọwọ ati Akintọla loo nsumọ etile, papa julọ Oloye Awolọwọ wa ni Calabar ọna ni si jin. Oloye Akintọla npe olowo ibo kakiri ipinlẹ iwọ o u."

Ọlọla Adesọjį ni ki nwọn ma fi orukọ on si inu awọn ti yio ṣe eto ipari ija na rara. Nitoripe ki ṣe asiko yi ni o tọ kia fi ọnu kan ija pipari rara.

Ẹgbẹ kan tį Alhaji R. A. Adesina da silẹ nį o da oruko ọlọla Aderẹmi pe on ni yio ṣe olori awọn ti yio pari ija na, Ọba Oni sọ n'nu ipade ti o ṣe pẹlu awọn o nį iwe irohin pe on ko mọ nkankannipaeto ipari ija na rara, o ni awọn ẹgbẹ na ko gba iyọda on ki nwọn to fi oruko on sinu rẹ.

Ọba Ọni ni Alhaji R. A Adesina pẹlu awọn kan wa si ọdọ on nipa a ti pari ija oloye Awolọwọ ati oloye Akintọla. Ṣugbọn mo sọ fun nwọn pe nko nį owo ninu rẹ ni asiko yi ti įsẹ ibo įle igbįmọ gbogbo-gbo gba ọkan gbogbo enia.

O ni on fi han won pe ki ẹ to le ṣe įru ikan nwọnyi ẹnį lati gba iyọda lẹnu ọgbẹni Awolọwọ atį ọgbẹni Akintọla siwaju.


## Plushes, Velvet, Velveteens, Damask

## & Building Materials

PLEASE CONSULT

## Okunowo Brothers

(63, Massey Street, Faji Market)

LAGOS NIGERIA

The House Where Courtesy & Satisfaction are Cuaranteed.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23379.

OLOTU B. A. CAREW 43. Offin Road, Lagos.

# Itan Igbesi Aiye Anobi Muhammed

**By Alhaji T. K. Oshishi**

بسم الله الرحمن الرحيم

Ninu awọn nkan iyanu ti a ri ni ọjọ ti a bį Mohammed ni pe, o wa si aiye pẹlu ọsọ Aṣọ ṣẹda funfun, Nigbati o wa ninu ẹje o gbe ori re soke latį fi han pe on ni asiwaju fun gbogbo ẹda.

Ninu nkan ami iyanu rẹ ni pe, nigbati o di ọmọ ti a nilatį lọ wọn ni ori iwọn Anobi Mohammed tẹwọn ju gbogbo iwọn įlu ati agbegbe rẹ lọ. O fi han pe on ju gbogbo ẹda lọ.

Lẹhin ti iya rẹ ti bi tan ti o fun nį ọmu, obinrin kan tį a npe ni Thuwaįbat tun fun ni ọmu ki awọn obinrin ti nwọn gba ọmọ tọ to wa si ọdọ Aminọt, ṣugbọn nigbati nwọn de ti nwọn gbọ pe ko ni Baba awọn tọra nfi ẹhin silẹ nitoripe nwọn ro pe ko si ẹniti yio san owo fun wọn ti awọn ba tọ ọmọ na tan.

Nigbati Haleemoh kiri ti kori ẹnįkan gbe ọmọ fun on na o pada pe ki on lọ gba Anobį bẹ ki oju ma ti on wọ inu eko nwọn.

Haleemoh pa a jẹobinrin kan ti o ni iwa irẹle ju awọn yoku re lọ to bẹ tį nwọn ko fi fun ni ọmọ tọ. Ṣugbọn nipa wipe Ọlọrun fẹ fi įsẹ rẹ han lorį awọn meiej Haleemoh wa gba Muhammed.



Awọn yi ko mọ iṣe Ọlọrun Ọba ẹlẹrọ ti nṣe iṣẹ rẹ ni ọna ara. Nwọn ko mọ wipe Muhammed na ni o nbọ wa di ọga awọn ọba ati awọn alaṣẹ orilẹ ede gbogbo aiye.

## Awon Ore Meta Ti Nwon Koie Ya Ara Won

(O bẹrẹ loju ewe kini)

jẹ o ni suru ati ọyaya si ọmọde ati agba.

Eyi Owu Awi jẹ agbẹ a si ma da oko fun tita ati jijẹ ni iwọn iba ti on pẹlu įyawo rẹ le jẹ, nigbati o ya iyawo rẹ ni oyun o sį bį ọmọ ọkunrin kan ti a sọ orukọ rẹ ni suru.

Nigbagbo ọjọ aįye Eyį Owu Awi, bi ẹwurẹ kan ko ba gbọ, ko ni ri aye lati parọ miįran, gbogbo owo ọja tį o si nta orį bukata ti įyawo ati ọmọ rẹ ni o mba lọ.

Koįu p ri.